# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 830 LAGOS SATURDAY JULY 28, — AUGUST 3, 1962. KOBỌMEJI (2D)


# Awon Alufa La'la pe omi

## FE YA W O'L U EKO

### NWON NI KI GBOGBO IMALE EKO GBAWE OJO KAN

EKO—Ni ana ọjọ Ẹti eyiti awọn Imale npe ni ọjọ Jimọ ni gbogbo awọn Imale Eko to lọwọ-lọwọ lọ si papa-ikirun ni Ọbalende lati lọ ṣe akanṣe adura fun idarijin fun ẹṣẹ awọn ara Eko nitoripe awọn Alufa kan sọ wipe awọn la ala kan omi ya wọ ilu Eko, o si ngbe tọmọde tagba lọ gẹrẹgẹ, ọpọlọpọ ẹmi ati dukia ni o si ṣofo.

Gẹrẹ ti awọn Imale yi ti kirun janma tan ni Mọsalasi Jimọ lana ni Lemọmu Agba, Alufa Tijani ti ṣe ikede ọrọ na fun gbogbo awọn janmọ, ti nwọn si mura ti nwọn gba Ọbalende lọ ke "kurusiu," nwọn kirun, nwọn si tun gba adura wipe ki Anọbi Mohamed (ikẹ ati iyin Ọlọrun ki o ma ba a) da ri gbogbo ẹṣẹ ikọkọ ati ti gbangba jin wa, ki o mọ jẹ ki ẹkun-omi kowa lọmọ lọ ati aya wa pẹlu awa paapa.

Onirohin Eleti-Ọfẹ ni ọkan ninu awọn baba Alufa ti o la ala na sọ fun on wipe Maleka ti on ri ni ki gbogbo ara Eko gba awẹ ọjọ kan ki nwọn si ṣe itọrẹ anu, eyiti nwọn npe ni saka.

Adura awa Eleti-Ọfẹ ni pe ki Ọlọrun jọwọ gba wa lọwọ ẹkun omi.

## Alufa Nsanra Ijo Nru


(WO OJU EWE KARUN)



THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS,

LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell

Telephone
London Wall 4303

Cable & Telegrams
Natbaniger ; London

Head Office Representative in London.
E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG


### Imale Ki Jo Baata

# Lamidi Ji Bibeli Ni Sobu

EKO—Laipẹ yi ni awọn ọlọpa Eko ti ọkunrin Imale kan ti orukọ rẹ njẹ Lamidi Ishọla, ara Isalẹ Eko, gbọngbọn lọ si iwaju Adajọ Kotu fun ẹsun w i p e o ji Bayibulu (Bibeli) gbe ninu ile itaja kan l'Ẹhingbẹti ni Eko.


(Wo yoku loju ewe kẹjọ)



LAGOS RACE CLUB

STARTING TODAY

August Race Meeting

First Race 3. 15 p.m.

Come One Come All.

Hon. Secretary,
Lagos Race Club.

# Awọ Irawo

## Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbọ.

AQUARIUS (Jan 22–Feb 20) Ọkan rẹ ni gbogbo ode ti o ba fẹ lọ a wa, ṣugbọn ki o ṣọra ki o ba mọ na inakuna. Orire wa fun ọ ninu iṣẹ rẹ. Isoro ti o wo fun ọ nipa ailera fun igba die ni.

PISCES (Feb 21–Mar 20) Ori yiya ati inu didu wa fun ọ, ki o si mura lati lo wọn fun nkan rere.

ARIES (Mar 21–April 20) Lọ si ọdọ dokita nitori aisan airorun sun. Ṣọra pelu ija larin awọn ebi rẹ.

TAURUS (April 21–May 20) Ṣọra pelu ọrọ ẹnu rẹ lọsẹ yi ki o mọ ko iyọnu ba ẹ.

GEMINI (May 21–June 21) Gbogbo nkan ti o bo se lọsẹ yi ni a dun mọ awọn aladugbo rẹ ninu wa si ri oju rere lọdọ wọn.

CANCER (Jun 22–July 23) Mura lati se nkan ẹtọ ti okan rẹ ba sọ fun ẹ wipe rere ni. Bi nwọn ba fi ọrọ ija lọ ẹ, ki o mura lati pari rẹ fun wọn.

LEO (July 24–Aug 22) Maṣe wahala pupọ lori nkan asan, ki o si fọkan tan awọn ti o ba nifẹ rẹ gidi-gidi.

VIRGO (Aug 23–Sept 23) Mafi iṣẹ ṣiṣe pa ara rẹ wa isinmi fun ara rẹ. Awọn nkan ti o ba ṣoro ṣe a mọ wa si iwaju rẹ ninu ọsẹ yi, ṣugbọn ajinde ara wa fun ọ.

LIBRA (Sep 24 –Oct 23) Ki o to lọ si irin ajo ki o ro daradara Otitọ ti o ba se ni a je ki o ri ojurere lọdọ awọn ti o feran rẹ.

SCORPIO (Oct 24–Nov 22) Kio gbidanwo lati turaka si ẹnikan ki o ba ri ifaa ko lọdọ awọn ti o ba npade.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Irohin okere kan ti ọ nreti, rere ni a ja si. Maṣe ba enia kan ṣe gbolohun asọ.

CAPRISCORN (Dec 23- [illegible]n 12) Gbogbo nkan ti o ba ṣe lọsẹ yi ni yio te awọn ti o ba mba pade lọrun. Mura lati je ere iṣẹ ọwọ rẹ.

# Awon Oyinbo UAC Fe Da Ilese Apoti Sile

Eko—Laipẹ yi ni awọn ẹgbẹ onisowo U. A. C. fi irohin kan si etigbọ wa wipe, pelu asowopọ awọn ẹgbẹ kan ti njẹ Thames Board Mills Limited ti Purfleet ni ilu Oyinbo, pelu awọn tinse olori onisowo Unilever ni asopọ owo lati da ibi iṣẹ apoti kan silẹ ni ilẹ Nigeria. Owo iṣẹ yi yio si na wọn ni nkan bi £1,000,000. Nwọn yio ma ṣe apoti panu ati ti pali, fun lilo fun ohun ọja tita ni ilẹ Nigeria.

A si ni ero wipe gẹgẹ bi iṣẹ aje ti ndagba si ni ilẹ yi beni ibere fun awọn nkan nwọnyi yio jẹki iru owo ti nwọn fẹ da iṣẹ na silẹ jẹ nkan ti o tọna, ati wipe a si nṣe iwadi boya a le ri awọn ohun elo, gẹgẹ bi takanda ninu eyiti a ti le ṣe pali na ni ilẹ Nigeria.

Awọn ẹgbẹ nwọnyi nṣe eto lati ri wipe awọn ara Nigeria jẹ alabaṣe ninu iṣẹ tituu yi laipẹ.


## ANNOUNCEMENT

THE NIGERIAN PORTS AUTHORITY has pleasure in annoucing that arrangements have been concluded for a NORTHERN REPRESENTATIVE (MALLAM ABDULLAHI OBADAKI) to be permanently domiciled in KANO in an office to be shortly opened in the new building of the Northern Region Marketing Board, Post Office Road, Kano.

A further anqouncement will be made as soon as a definite opening date has been fixed.

**BAYO KEHINDE**
Secretary to the Authority.

NPA Notice No. 733
25th July, 1962


# Alakoso Ijoba Gesi Yin SLA Ati Awo

Gudugbẹ kan ti Oloye Michael Okorodudu tiṣe aṣiwaju awọn Lọya agbẹjọro awọn Oluwadi ti awọn nṣe iwadi awọn Ajọda - iṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ orun gbe silẹ ni iwe kan ti o sọ wipe nwọn mu ẹnu kan Ọgbẹni Harold Macmillan, Alakoso ijọba ilu Gẹsi ninu ọrọ adehun iṣẹ larin Oyinbo olowo onisowo iwe irohin kan, Ọgbẹni Roy Tomson, pelu awọn ti o ntẹ iwe irohin kan l'Eko, awọn onisẹ Amalgamated Press ti awọn ntẹ iwe irohin ojojumọ ti njẹ DAILY EXPRESS.

Okorodudu ni ki Oyinbo olowo onisowo iwe irohin yi to ba wọn ṣe aṣepari adehun lati jọ ma tẹ iwe irohin pọ ni nwọn ti sọ fun un wipe Ọlọla Alakoso Ijọba Gesi paapa ti wipe ki Oyinbo yi fọkan ara rẹ balẹ nitoripe awọn enia meji tiṣe olori fun awọn ẹgbẹ onisowo ti o mba ṣe adehun, awọn Oloye Awolọwọ ati Akintọla, awọn ni on lero wipe nwọn le ṣe alakoso Ijọba Apapọṣe (Federal Goverment) ti yio fẹsẹ mulẹ gbọingbọin ni Nigeria lọjọ ọla.


ELETI–OFE
DARABA
E Ma Ka iwe Irohin
Eleti-Ofe.

### EGBE ONIBODE DE!

# Fayawo Ko Ni Si Mo

### (Lati owo Olofintoto)

IGỌLỌ, DAHOMEY—A gbọ wipe laipẹ yi awọn Ijọba ilu wa mẹta kan——ilu Nigeria, Dahomey ati Togoland ngbero lati t'ọwọ bọ iwe adehun kan lori ọrọ ibode (Customs Union) ti o pa awọn mẹtẹta pọ ki awọn si fọ'gba ayanga le awọn ti nṣe iṣẹ FAYAWỌ lori. Lati le mu iṣẹ yi ṣe, ọpọlọpọ igba ni awọn ọga iṣẹ-ibode awọn ilu mẹtẹta ti a darukọ yi ti ṣe ipade ti nwọn si ti jiroro lori ọrọ na.

Onirohin Olofintoto Eleti Ọfẹ ti o lọ si Igọlọ ni ilu Dahomey laipẹ yi ni on gbọ wipe bi nwọn ba ti da ẹgbẹ Onibode yi silẹ nkan ni lati rọrun fun awọn arinrin-ajo ilu mẹtẹta na; kosi ni si wipe a nṣe wahala antu ni si ihoho, a nyẹ ni ọwọ ni igba igba ni bi na mẹrin mọ.

Tẹlẹ tẹlẹ bi o ba fẹ lọ si ilu awọn Dahomey, ti o dide lati Nigeria, o kọ ni lati lọ fi pọnun mẹta ati abọ juba ni ile iṣẹ awọn Ijọba Dahomey na ti o wa l'Eko ti nwọn npe ni Dahomey Embassy, iyẹn lẹhinti o ba ti gba iwe-aṣẹ ti nwọn npe ni Travelling Permit tabi Passport lọwọ Ijọba Nigeria.

Ti o ba de Idiroko, eyi ni ipinlẹ ala larin ilu Nigeria ati awọn ara Dahomey, awọn akọwe ibode a yẹ ẹ wo. Ayẹwo ti kii ṣe yẹyẹ ni o.

Maṣe lero wipe o bọ ninu wahala ayẹwo awọn akọwe ibode ati ti awọn ọlọpa ti o ba ti kuro ni Idiroko na, nitoripe ti o ba ti rin kuṣẹ diẹ siwaju ọwọ awọn akọwe ibode ilu Dahamey ni o bọ si. Ṣe iwọ na mọ wipe awọn Oyinbo Faranse yi ni nwọn tọ wọn ? Nitorina nwọn KOGBA GBẸRẸ RARA. Nwọn a yẹ ọ wo tojutoju ati timu timu.

O ko gbọdọ ba wọn ja iyan tabi ki o gbo wọn lẹnu. Nigba yẹn o ti bọ si ipinlẹ awọn Dahomey yi ti nwọn npe ni Igọlọ. Ni ilu Dahomey gaan, ibi kan wa ti nwọn npe ni Grand-Popo, awọn ara ilu Dahomey yi a tun yẹ ọ wo ati gbogbo awọn nkan ti o di sinu apo-ẹru rẹ na.

Bi o ba jẹ wipe o nti ilu Ajaṣẹ bọ ti o si mu ọti Oyinbo bi waini (vine) tabi wisiki (whisky) lọwọ nitoripe iru awọn ọti lile bayi pẹlu siga ati ewetaba rọ ni Ajaṣẹ, owobode ti wa san lori awọn ẹru na gọbọyi ni.

Ṣugbọn nisisiyi awọn Alakoso Ijọba ilẹ Nigeria ati awọn Alakoso Ijọba ilu Dohemey pẹlu Togoland ti nfi ori ara wọn k'ori lati jiro-ro nkan ti nwọn yio ṣe nipa owo'bode larin awọn ilu mẹtẹta ti wahala ko fi ni si larin awọn onisowo alajapa ti nwọn ba nṣe iṣẹ ọwọ larin awọn ilu ti a darukọ wọnyi.

Eto ọrọ adehun na si ti nfidi mulẹ larin awọn Alakoso Ijọba ilẹ Nigeria ati Dahomey nitoripe ninu ọsẹ ti o kọja yi ni Ọgbeni Bertin Borna, Minisita Alamojuto eto owo Ijọba ilu Dahomey na wa si Eko lati wa ba Oloye Festus Okotie-Eboh, Minisita Alamojuto eto Owo Apapọ Ijọba Nigeria lati ṣe aṣepari iwe adehun wọn na.

A gbọ wipe nwọn ti mu iwe-adehun na fun awọn ogunna-gbongbo Ijọba ilẹ mejeji, ki nwọn le wo o finni-finni, ki nwọn si fi ọwọ si i.

Ti nwọn ba ti ṣe eyi tan, ọna a wa di fun awọn ti nṣe iṣẹ FAYAWỌ (smugglers) lọna Tagbe, Idiroko, Igọlọ ati Porto Novo.

## OGBENI S. ADE MARTINS ORUN RE

ṢHOGUNLẸ—Laipẹ yi ni a gbọ wipe Ọgbẹn Samuel Adegunlẹ Isabade Martins jalaisi lẹhin aisan diẹ ti o ṣe ni ibiti o ngbe ni Ṣhogunlẹ leti Eko. Gbara ti nwọn ti tu ọfọ rẹ ni ẹsẹ awọn ọmọlẹbi ologbe yi lọkunrin, lobinrin ati lọmọde lagba ti pe ṣiba siba si ibi oku na.

Awọn bi Alufa (Rev) A. Adegboyega, Ọgbẹni Ọkẹ ati aya rẹ, Ọgbẹni E. A. Jọda ati aya rẹ, Ọgbẹni S. M. Olumuyiwa, Ọlalekan Ọnatade, Iyafin Ọrẹ Johnson, Mọrinade Johnson, Dunni Johnson ati awọn Ṣobayọ.

Ologbe yi jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Oke Ago-Owu ni Abẹokuta ti nwọn ri owo ṣe nigba aiye Koko (cocoa) ni iwọn ọdun gbọrọ sẹhin, o si fi owo rẹ na mọ ẹbi ati awọn ọrẹ rẹ.

Fun iwọn ọdun diẹ ni o ti wa ni ilu kan leti Onitsha ki o to pada wa sile. A ki iyawo rẹ (alarede) Gburo ọmọ Pa Leigh ati Nora pẹlu awọn ẹbi bi Oloye J.K. Ajala ni Agọ Ijaiye l'Abẹokuta, Iyafin Clara Johnson ati akọbi ọmọ rẹ, Akanni Martins, nwọn ku aṣẹhinde.

# Sardauna Alakoso

### Ijoba Ipinle Ariwa Ni Ilu Oyinbo



Aworan'oke yi ni igbati Ọtọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto tiṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa Nigeria, mbọ Ọgbeni Harold Macmillan, Alakoso Igbimọ Ijọba Gẹẹsi (British Prime Minister) lọwọ wipe o digba, lẹhin ti O'ọla Sardauna ti ba Ọgbeni Macmillan jẹ onjẹ-ọsan ti o pe e si ninu ile ti Alakoso Igbimọ Ijọba Gẹẹsi na ngbe ni London.

# ELETI–OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 468        Phone 23370.

VOL XIV. No. 830. SATURDAY JULY 28,-AUGUST 3, 1962.


## A Ki Gbele Gb'ofa

Awọn Yoruba ni nwọn nma npa owe wipe "igi gangangan mọ gun mi loju, okere ni a ti nsọ". Iyẹn ni wipe bi enia kan ba ri ogulutu jamba kan ti nwọn sọ si on lati okere, on paapa a tete ya yẹ kuro ni aṣa ibiti ogulutu yi mbọ. Eyi ni ọrọ ikilọ ti a fẹ ṣe fun awọn ọlọpa wa ati ọpọlọpọ awọn onworan ti o jẹ asa wọn lati ma lọ to sori kereni pajawiri kan ti nwọn ṣe fun awọn ti o fẹ rekọja si odi keji oju titi ni Idumọta l'Eko.

Awa onwe irohin Eleti Ọfẹ ṣe akiyesi a si tun ronu jinlẹ lori nkan ti a ri ni ijeje ọjọ Aiku ti nwọn sọ wipe oṣelu kan fẹ wọlu. Lati owurọ kutu hai ni ọpọlọpọ awọn alairiṣẹṣe kan ti lọ ko ara wọn jọ sori kereni pajawiri yi ti nwọn ko jẹ ki awọn ẹlẹsẹ ti nwọn ti itori ti wọn kọ kereni na ribi gba kọja sọda si odi keji titi nitori ijamba ogunlọgọ mọto-ayọkẹlẹ ti nwọn nsare kọja wiri wiri.

### Lailo Ogun

Nwọn ni diẹ ni ọrọ ti Alaba ninu ọrọ awọn ibeji, ọrọ Idowu ni o kanpa. Diẹ ni ewu ijamba ti a ṣe akiyesi ninu ọna ti awọn alainiṣẹ yi di fun awọn ti nwọn fẹ rekọja s'odi keji, sugbọn eyiti o ba wa lẹru ni ti ọkẹ aimoye ẹmi ti o le ṣegbe sibẹ ti kereni pajawiri na ba jabọ nitoripe ko nṣe nkan ti o ni agbara rara ati wipe nwọn ko si kọ fun ogunlọgọ enia lati duro lori rẹ.

Tito bi o ti le jasi ki o jasi ni awọn enia lọmọde lagba to si ori kereni na lọjọ ti a wi yi.

Nitorina a fi si eti gbogbo awọn ọga ọlọpa ki nwọn maṣe gba awọn enia laiye ju awọn bi mẹdọgbọn lati to sibẹ lọ lọjọkọjọ ti nwọn ba ni ohunrere kan lati ṣe lẹba ibẹ. A si tun ṣe ikilọ fun ẹnyin ara ilu Eko, ki ẹ ye fi ẹmi yin w'ewu.

A ki gbele gb'ọfa lailọ si oju ogun.

# Iwe Si Olotu

## Nitoto Atigbe'yawo Ko Ja

Ẹ jọwọ, alagba, mo gbadun asọye ọrọ (editorial) yin ti ẹ kọ laipẹ yi ti ẹ ni ATIGBE IYAWO KO JA, OWO ỌBẸ NI O ṢORO. Nitotọ ododo ọrọ ni ni aiye atijọ sugbọn ko nṣe lọdọ awọn ọmọ ode ti isinsinyi.

Lokunrin ati lobinrin wọn ko si eyiti o nsun ninu wọn. Ti nwọn ba ti le ri owo na nibikibi lati le fi ra aṣọ ati bata ni Gbagi ni Ibadan tabi fi ra lali-ele l'Ẹhingbẹti ni Eko, ti nwọn ba si ti ni aṣọ "bonfo" meji lati ri ohun mu lọ ile ijọ ni Kubanbanka, iyawo ti de.

Ọkọ paapa o ti rii si? O le pe obinrin mẹrin lẹkan ṣoṣo; iro ti a ma gbe fun wọn.

Ẹ ṣe Olotu, ti ẹ nsi wọn leti. Ọlọrun jẹ ki nwọn ko gbọ.

Emi ni,
Ibadan        Joseph Akande

## Eru Aiye Mba Emi Na

Olotu,

A gba fun itan aladun ti ọkan ninu awọn ọsọtan yin, Ọgbẹni J. Ọla Wins nkọ ninu eyiti o wipe Ẹru Aiye Mba On. A fi aṣiwere enia ni yio sọ wipe ẹru aiye yi ko ba on rara.

Ṣe ẹniti o nfẹ ki nkan tirẹ ko dara ti o si dara ti o si jẹ wipe bi tirẹ yio ṣe bajẹ ni o nwa ni o wa sọ wipe ẹru iru enia bẹ kotilẹ ba ọ? Tabi ẹniti o mba ọ jẹ, ti o tun mba ọ mu, ti o wa ṣetan ti o nsọrọ rẹ ni buruku lẹhin?

Bi enia ba ri ọmọ araiye ti ko sa ori rẹ loburu. Ọrọ ọmọ araiye kanpa o

Olotu, ẹ jẹ mo wipe mo ti fi awọn iwe Eleti Ọfẹ ti ẹ tẹ itan na si ranṣẹ si ọmọ mi ni ile ẹkọ wọn, ki o ka, on ati awọn ẹgbẹ rẹ.

Emi ni,
Abẹokuta        S. Ọlanipẹkun


OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE

TI ỌJA LE FI MA TA
BI IṢU AKARA GBIGBONA.
POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI–ỌFẸ

ELETI--OFE
DARABA
E Ma Ka Iwe Irohin
Eleti-Ofe.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## ALUFA NSANRA, IJO NRU

Iwonyi ni ọrọ ti Oloye Michael E. R. Okorodudu, aşiwaju agbẹjọro fun awọn oluwadi ti o nşe iwadi awọn Ajọda-işẹ mẹfa ti Ipinlẹ Iwọ Orun sọ nigbati nwọn berẹ ọrọ iwadi na ninu ile Igbimọ-giga (House of Senate) ni owurọ ọjọ Ajẹ ni ijẹta.

Oloye Okorodudu ni awọn ọrọ pataki kan wa ti on a fẹ ki awọn oluwadi na şe abẹwo yekeyeke, awọn ni ọrọ awọn ẹgbẹ onişowo kan ti o nkọ ile kiri bi ẹyẹ ti awọn ti awọn nşe iwadi rẹ yi fun ni owo gọbọyi lati ma fi kọ ile kakiri ni agbegbe ti kişe Ipinlẹ Iwọ Orun.

Kini o şe ti nwọn fi ya Dokita Akinọla Maja ni £120,000 lati fi da işẹ awọn apẹja kan ti nwọn npe ni Nigerian Fishing Company silẹ, nigbati o jẹ wipe nkan ti Dokita Maja na fi duro fun gbese yi ko ju £40,000 lọ?

### Ola-O-Jo

Oloye Okorodudu ni on ni awọn ẹleri jaburata ti on yio pe lati sọrọ, lati fi han gbogbo awọn ara ilu wipe awọn ogunna-gbongbo mẹrin ninu awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ni o ni ẹgbẹ kọlekọle kan ti nwọn npe ni National Investiment Properties Company Ltd (NIPC)' atipe £6,210,000 ni gbogbo owo ti awọn Ajọda-işẹ ti awọn nşe iwadi rẹ ya wọn.

Agbẹjọro iwadi na ni awọn Oloye S. O. Shonibarẹ, Oloye Alhaji Sule O. Gbadamọşi, Oloye (Dokita) Akinọla Maja ati Ọgbẹni Alfred Rewane ni awọn ogunna-gbongbo mẹrin na ti o ni ẹgbẹ onişowo kọlekọle yi.

O tun şẹ alaye siwaju fun awọn Oluwadi na wipe ko si ẹnikan ni gbogbo Ipinlẹ na ti awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun na ko Ọkẹ-aimọye owo fun bi iru ti awọn ẹgbẹ onişowo kọlekọle yi, bẹ Ijọba Ipinlẹ na ko lọwọ rara ninu işẹ ile ti nwọn nkọ kiri.

### Ani-kan-jopon

Oloye Okorodudu ni ọrọ na fẹ fi ara jọ iwa ANI-KAN-JỌ'PỌN, nitoripe nigbati awọn Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun da Ajọda-işẹ ẹgbẹ ile (Housin Corporation) silẹ ni Ipinlẹ na eto ori-ko-ju-ori lọ ni nwọn fi to o, iyen ni wipe ile kan fun ẹnikan; sugbọn nigbati gbogbo ọrọ na yanju tan awọn ogunna-gbongbo ti nwọn fi şe olori-eto ibi işẹ na ni nwọn npin awọn ilẹ-ile na ni fun ara wọn.

## Egbon Mu, Aburo Mu

Nwọn sọ ọrọ ilẹ na di ti ọmọlẹbi; bi ẹgbọn ti nmu bẹni aburo si nmu tirẹ.

Ki Ọgbẹni agbẹjọro yi to mu ọrọ rẹ ọjọ na wa si ipari o fi ẹnu kan bi nwọn tişe ya orişirişi ẹgbẹ onişowo miran yatọ si awọn ti a ti mu ẹnu kan yi ni owo iyakuya. Awọn bi ile ibişẹ ti nwọn ti nşe awo-targanran ni Ikorodu (Ikorodu Ceramic Industry) ti awọn Alhaji S. O. Gbadamọsi, £50,000 ni nwọn ya wọn; awọn işẹ alapako ati oko rọba ti Joseph Asaboro Limited ya £350,000 nigbati o jẹ wipe owo ti awọn onişẹ yi alara paapa ni lọwọ koju ẹgbaji pọnun (£4,000, ni owo gidi lọ ki nwọn to ya wọn lowo yi.

### Igbese Wa

Nitotọ awọn osisẹ ti o wa labẹ awọn onişẹ Joseph Asaboro yi le ni ẹgbẹdogun enia, awọn onişẹ na si ni ẹru owo iyebiye bi oko-rọba, igbo-gẹdu, ile ẹrọ afagi lọ bi rẹrẹ pẹlu pako ati awọn nkan bẹbẹ lọwọ, sugbọn gbese wa fun wọn ni banki (Bank) lati san, nitori eyi lo jẹ ki nwọn wa owo ya ti nwọn fi de ọdọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Aye si wa ninu adehun ti Ijọba Ipinlẹ na ba awọn onişẹ na şe lati mọ bojuto işẹ na tabi lati gba işẹ na lọwọ wọn ti nkan ko ba lọ dede ki owo ti nwọn ya wọn le wọle.


E kilo fun omo yin




Ki Nwon Mase Fomi Sofo

# Eru aiye ma mba mi (5)

### (Lati Owo J. Ola. Wins)

## Aiye Toto

GẸGẸBI inu ọrẹ wọnyi se dun si ọrọ apọnle ati ifọkanbalẹ ti awọn ọrẹ rẹ sọ fun wipe awọn yio ran lọwọ, atipe bi o ti bọ sita tan ti awọn ọrẹ rẹ yi kanna si bẹrẹ si yin imu si i.

Iṣẹ akọkọ ti ọkunrin yi ri nigbati nwọn ti daa duro tan, owo iṣẹ na ti lere ju, o fi ọrọ na lọ awọn ọrẹ rẹ ti nwọn jọ ngbe wo, nwọn ba damọran wipe ki o ma ṣe se iṣẹ na, o ni onjẹ nkọ? Aṣọ wiwọ panpa nkọ? Nwọn ni ki o fi ọkan rẹ balẹ awọn ti wa fun un, bi o ba ti ri awọn ki o mọ fo'yu. Ko sise iṣẹ na mọ.

Bi o ti sọ fun wọn wipe on ti gbọ ti wọn, inu nwọn dun nwọn ni ọwọ tẹ were yi wayi, ṣe o ni on ko mọ ọkan, a mọ meji nigbati o ba ya.

## Oju Aiye Re

O tun gburo iṣẹ miran, kaka ki o ṣe ọrọ na ni oruko oloruko kan ti o njẹ "IMỌNU" ki o si fi ọrọ na si ikun ara rẹ; o tun ko, o tun ro fun awọn ọrẹ rẹ alabosi yi, nwọn tun gbe ọgbọn ẹrọ bọ lọwọ, o tun fi iṣẹ na silẹ.

Gbogbo ojulumọ ọgbẹni yi ti nwọn mọ wọn ni o ntu irọ ati asiri ti awọn ọrẹ nṣe si yi fun un, ko gba, o ni aiye fẹ ba ọrẹ awọn jẹ ni, to sile bajẹ, ko mọ wipe ni ara on ni iso gbe ti nrun. O fi inu we'nu, o ko wọn mọra, a ṣe ọta ni o npe ni ọrẹ. Oju aiye ni e ri nyẹn o? Bi eni ko ba mọ ri, ko mọ ni sọ.

Ọgbẹni kan sọ wipe "maṣe rọ wipe Lagbaja fẹran rẹ, a fi wipe o fẹran Lagbaja".

Iṣẹ miran tun yọju ni ọdọ ara adugbo wọn kan o jẹ iṣẹ ilẹ gbigba, aladugbo nwọn na wa pee si ikọkọ, o ni ni "wa o, bi o ba fi ọrọ yi lọ awọn ọta rẹ, iya yio jẹ boto si ọ lara, nitoripe ọta ni o npe ni ọrẹ. O tun sọ fun wipe ṣe o mọ wipe a jọ ngbe adugbo kanna ni" ? Ọgbẹni yi kọ jalẹ ko gba ọrọ na gbọ rara. Se aja ti yio ba sọnu ko ni gbọ fere ọlọdẹ ni ọrọ naja.

Obinrin kan wa ni adugbo awọn ọrẹ yi, gbogbo bi awọn ọrẹ yi ti mọ nṣe ako loju rẹ, ti nwọn mọ fi ọrẹ olore yi ta'yin ko dun mọ arabinrin yi ninu rara. Nigbati ọrọ iṣọkuso yi kua eti arabinrin yi, arabinrin na tọ ọkunrin yi lọ, o ko, o rọ fun un, o gba diẹ gbọ sugbọn ko gba awọn miran gbọ ninu ọrẹ na. Gbogbo awọn ọmọ aiye ti o jẹ aladugbo ni o nṣe ofofo nipa ọrọ ti awọn ọrẹ rẹ nsọ lẹhin rẹ. Bi inu rẹ tiri ni o ṣe fi nhuwa.

## O De Gongo

A samọ samọ awọn ọrẹ yi ti ṣe eto ati ja ọrẹ wọn olore yi silẹ, nwọn ko san owo ile osu meji, ṣe on ni o fi ọwọ ara rẹ gba ile iọdọ awọn ti o nmọ fi ile haya lati gbe. Gbogbo eru nwọn ni nwọn fi ọgbọn sa lai ku eenu kuro ninu ile na. Ṣe oni pọtimọto ni nwọn, nwọn ko ni aga, nwọn ko tun ni nkan ọṣọ ile kankan rara.

Nigbati oṣu kẹta pari, nwọn jakun ọrun wọn, nwọn lọ we ile ti nwọn sọtọ, wọn ni awọn ko le da eesu ada ko mọ.

Nigbati ọgbẹni yi ko ri awọn ọrẹ rẹ na mọ, ko mọ eyiti yio ṣe, ko si mọ nkan ti o ṣẹlẹ. Bi o ti ji lowurọ ọjọ kan ni o ri iwe kekere kan ti o ka bayi, "a ri wipe ile yi ko gba wa, a si ti ba ẹsẹ wa sọrọ, ati pe iwọ ko tilẹ fẹ nkankan ṣe rara; awa ko le ba ole gbe o, a yapa nipa ti ara sugbọn ki ṣe nipa ti ẹmi. Gbogbo ore ti o ṣe fun wa a ti san fun ọ pada ni aimoye igba. Oju ko fẹ ara ku, awa ni tirẹ nitoto, Lagbaja ati Tamẹdu."

Bi ọgbẹni yi ti ka iwe yi tan, ni o ba daku lọ rabidun, o to ọgbọn iṣẹju ago ki ọkan rẹ to sọji. Bi ọkan rẹ ti sọji ni o ba ranti awọn owe ti o wipe, "ẹniti a ni ki o fẹni loju fi ata sẹnu, ẹniti a ni ki o kinni lẹhin fi ẹgun sọwọ, ẹniti a ni ki a fẹhinti ki a mu didun ọsan, kikan ni o nfun ni mu."

(Koi ti pari)

---

# Ilu Ibadan Dasi Meji Lori Oro Egbe Akintola

IBADAN—Laipẹ yi ni gbogbo awọn oṣelu ti awọn ara Ibadan yan si ile Igbimọ Oke Mapo wipe ki nwọn mọ ṣe aṣoju fun awọn, fi imọ sọkan wipe ẹgbẹ Ọlọmọ ti Oloye Akintọla ṣẹṣẹ fe gbe jade ni awọn fẹ ṣe nitoripe aigba aiye Oloye Akitọla yi ni awọn tun ṣe ọmọ ẹbi.

Oloye Augustus Akinloye, ti ṣe alaga Igbimọ na si ṣe alaye wipe on ko fi ipa mu ẹnikan wipe ko ṣe ti ẹgbẹ kan, ṣugbọn on ri wipe ko si ẹgbẹ kan ti o le gba iyi ju ti Oloye Akintọla lọ. Lẹhin alaye yi, diẹ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ igbimọ na si f'aramọ ọrọ Oloye Akinloye.

## Ilu Dasi Meji

Sugbọn nigbati ogunlọgọ awọn ti o pejọ sita gbọ nkan ti o ti ṣẹlẹ ninu ile igbimọ na, nwọn lọgun too! Nwọn ni awọn ko faramọ ọrọ awọn igbimọ na, nitoripe bi awọn ko ba mọ ibiti awọn gbe nlọ, o yẹ ki awọn mọ ibiti awọn gbe ti mbọ.

Nwọn ni ṣe Oloye Akinloye yi na ni o fa awọn sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) lọjọ ti o ti pẹ, on na ni o sọ wipe ẹgbẹ na "a-wi-mọ-yẹun" ni wọn, ki lo ti wa fa a ti ẹ ni ki a kuro lẹhin wọn ? Gbogbo wọn si fi akekọri, ilu si dasi meji lori ọrọ na.

# More New Lawyers For Nigeria

## 53 Called To Bar In London

LONDON—More Nigerian students were called to the Bar in the four Inns of Court in London last week than from any other country in Africa and probably more than from any other overseas country during the Trinity term.

In all fifty-three students from many parts of Nigeria achieved the distinction together with sixteen from Ghana and three from Sierra Leone.

Called to the in Bar in LINCOLN'S INN were: Samuel E. O. Okusipe of Apapa; Yetunde O Onayemi of Lagos; Gabriel G. I. Ojiako of Port Harcourt; Isola A. Azees-Olorunnibe of Yaba; Charles C. Moneke of Zakirai via Kano; Pater C. Nwagbogu of Onitsha; Adeyemi A. Osibogun of Lagos; Dennis I. O. Ewelukwa of Onitsha; Mosurudeen A. Kuku of Ijebu Ode; Joseph O. Irukwu of Aba; Karimu O. Latunji of Ibadan; Theophilus O. Adeniran of Ibadan; Olaniwun Ajayi of Ijebu Remo; Mubashiru A. O. Ab ru of Lagos; Gabriel O. Iredu of Onitsha; Daniel A. Ladega of Lagos; Oritsegbiten Edodo Siluko via Benin City; Fredrick A. C. Enwonwu of Onitsha; Popoola Balogun of Oshogbo; Ajibade Sanni of Iwo; Olushola A. Fadahunsi of Ilesha; Taiwo Aribisala of Ijebu Jesha via Ilesha; Nonilola A. Abiola of Ibadan; Ajagbe T. Oyewo of Ibadan; Isaac O. Jemide of Sapele.

GRAY'S INN were: Edmund N. Uzodike of Enugu; Charles N. Oniah of Umuascle Omotisha; Loveday A. Iyagba of Okika; Mignon Princewill of Buguma; Kenneth K. A. Keazor of Ebute Metta; Samvel O. Ogedengbe of Ilesha; Emmanuel N. Okuzu of Ojoto Onitsha; Samuel O. Shonola-Shoyinka of Abeokuta; Donald B. Coker of Lagos.

The MIDDLE TEMPLE were: Olufunmi O. Jibowu, Lagos; Francis N. Chukuani Uwani-Unugu; Guy I. Ikokwu of Port Harcourt; Gabriel O. Sodipo of Ebute Metta; Patrick B. Azike of Onitsha; Samuel Ebele of Ewokoye Awka; Mrs. Leila E. Fowler of Yaba Estate, Lagos; Idowu Sofola of Ikenne—Remo; Nuhu Usman of Okene; Joseph O. Agarin of Aragba, Urhobo Division; Isaac A. Osinoiki of Surulere; Lawrence C. Anoliefo of Aba.

(contd. on p. 8)

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas, Talisman, Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 10 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

## Pastor King Fights Colour Bar In America

GEORGIA, U S A — The Reverend Martin Luther King, Negro civil rights leader, recently released from jail against his will, said he will remain here to continue his protest against recial segregation practices.

Dr. King and a fellow minister chose jail rather than pay a fine for violating a local ordinance. They had served two days of a 45-day term when the fine was paid by an unidentified man and they were released.

Shortly after his release, Dr. King said he would remain here until city officials agree to drop charges pending against some 750 demonstrators arrested since last December, when a dispute began over racial discrimination in bus and rail terminals, and until officials establsh a biracial-committee to discuss desegregation of public facilties here.

Dr. King said "some progress" was made but no further conferences had been scheduled. Dr. King said he "could not in all good conscience, leave here until these cases have been resolved."

Pastor of local Church, Dr. King achieved worldwide attention several years ago for his role in fighting—and eventually eliminating—racial segregation on buses in Montgomery, Alabama. He is now President of the Southern Christian Leadership in Geogia, America.

## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO, TENDER SCRAPS.

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of Scrap materials now lying at the Authority's premises at Port Harcourt.

2. A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, or Port Manager Eastern Ports, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt, on payment of a deposit of £5 (Five pounds) to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays, or to the Area Accountant, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt. The completed tender form should thereafter be addressed to the Secretary to the Authority in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP MATERIALS" so as to reach him not later than 11th August, 1962.

3. The successful tenderer will be required to remove the Scrap at his own expense within 7 days of the acceptance of his offer. The deposit of £5 ( Five pounds ) will not be refunded in any event to any tenderer who, upon being advised of the acceptance of his tender fails to pay for and remove the Scrap. He will also be required to make necessary arrangements at his expense for the Scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

4. Tenderers are warned that Scrap available for disposal may comprise both ferrous and non-ferrous materials, although it is expected that most of the material will be ferrous.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE.
Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice NO. 732.
23rd July, 1962.

# Imale Ki Jo Baata

## Lamidi Ji Bibeli Ni Sobu

Awọn ọlọpa ni lọjọ ti nkan yi ṣẹlẹ, Lamidi lọ si inu ile itaja kan ti nwọn npe ni Kingsway Stores, o bẹrẹsi wo ọja ti nwọn patẹ kakiri, ko mọ wipe bi on ti n l ọ kakiri yi ni awọn ọtẹlẹmuyẹn ile itaja na nsọ on. Bi o ti de ibiti nwọn patẹ iwe Bayibulu yi si ni o ba f'ọwọ kọ ọkan, o si yi mọ inu agbada rẹ o bọ si ita; o ti de oju titi mọto ki awọn ọtẹlẹmuyẹn na to lọ ni agbada mu pẹlu iwe Bibeli na ti o gbe.

Adajọ kotu ti o nṣe ẹjọ ọdaran na bere l ọ w ọ awọn Ọlọpa wipe "mo ṣebi Imale ni ẹ pe Ọgbẹni yi kilo fẹ fi Bayibulu ṣe nigbati iko nṣe Alukurani"? Ọga ọlọpa ni ko ye on si. Gbogbo bi nwọn ti nda a, ti nwọn si ngbe e, nṣe ni ọdaran Lamidi yi nwo payiko ninu apoti.

Bi nwọn ba ti ro ẹjọ na si ẹo mọ gbọ nigbamiran.


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

INVITATION TO TENDER-ATLANTIC TERMINAL CATERING

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the provision of catering facilities at the Atlantic Terminal, Apapa Quays, on the days of arrival and departure fo Mailboats for a period of three years commencing on 1st September, 1962.

2. Tender Documents, giving details of the services to be provided and setting out the general conditions of the contract may be obtained from the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, on deposit of the sum of £5 which shall be returned by the Authority on receipt of a bona fide tender.

3. The deposit of £5 should be made to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays.

4. Tenders should be enclosed in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL - ATLANTIC TERMINAL CATERING" and forwarded to the undersigned so as to reach him not later than 4 p.m. on the 9th August, 1962.

5. The Authority is not bound to accept any tender.

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice No. 748.
27th July, 1962.



# Polowo oja re

Sinu Iwe Irohin Eleti–Ofe Losose


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Compay, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; EDITOR (OLOTU): OLA. ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos,

# Awon Oniwe Irohin Meji Gba Iwe Ihamo

Ni ijeri ti ise ọjọ'Ru (Wednesday) ni Dokita Adekoye Majẹkodunmi tiṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun paṣẹ wipe ki nwọn ha awọn oniwe irohin meji kan ni iwe ihamọle apapandodo g gẹbi ofin pajav'iri ti Ijọba Apapọṣe Nigeria (Federal Goverment) ṣe.

Awọn akọwe irohin (Journalist) meji na ti nwọn ni ki nwọn kuro l'Eko ni Ọgbẹni Lateef Jakande, ẹniti gbogbo ilu mọ ni "John West" ti o ba nkọ iwe, gege rẹ gbo, erekuṣu Burutu ni ofin ni ki o lọ, Ọgbẹni Jakande yi ni ọga awọn ile iṣẹ ti o ntẹ iwe irohin fun awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG). Ẹnikeji ti ofin mulọ si Forcados ni Ọgbẹni Victor Bisi Ọnabanjọ, ẹniti gbogbo ara Nigeria mọ ni "AIYEKOTỌ" gẹgẹbi orukọ ti o nfi kọwe sinu iwe irohin; ogunna gbongbo ni Ọnabanjọ ninu awọn oniwe irohin, o si tun jẹ ọga agba nibiti nwọn gbe ntẹ awọn iwe irohin ti a npe ni "Daily Express" ati Sunday Express ni Eko.

Ki Ọgbẹni Ọnabanjọ ti a npe ni "Aiyekotọ" na to kuro ninu ile rẹ lọ si Forcados o fi ye Ayiluka Eleti-Ọfẹ wipe ẹru kalamu tabi gege on ni o mba Dokita Majẹkodunmi nitoripe o ti gbọ wipe on fẹ tuna aṣiri gbogbo mago-mago ti nwọn ṣe nipa ile rẹ ti nwọn npe ni Lion Building ti o ta fun Ijọba Apapọṣe l'Eko.

"Aiyekotọ" ni lori ile ọkẹ meji o le ẹgbẹdọgbọn ponun (£45,000) ere ilọpo mẹta ni nwọn ri lori ile na nitoripe £159,000 ni ere ti nwọn jẹ lori rẹ.

O ni pe on ko ni sọ ọrọ na fun araiye gbọ, a fi ti nwọn ba ti on mọ'le lọgba ẹwọn.

## New Lawyers

(Contd. from p. 7)

The INNER TEMPLE were: Olusegun B. Awolowo of Ibadan; Simeon M. Ojkwu of Akano Item Bende Division; Joseph O. Ugoagwu of Mbaise-Owerri; Geoffrey C. Ohen of Owa Alizomo Agbor; Rita C. Modebe of Onitsh , Okechuku Adimora of Nanka-Awka; John A. O. Ojiako of Onitsha.


# A.G.Leventis & Co

## (NIGERIA) LTD.

For your shopping convenience we undertake prompt

## HOUSE DELIVERY

for our Ikoyi, Lagos Island, EB. and Yaba customers

**Phone Your Order to 24831 Ext. 32**

And

**We Open Our Mainland Supermarket And Cold Store On Saturday Afternoons**

**2. 30 - 5. 30**